# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL. XIV NO 920 LAGOS SATURDAY MAY 9—MAY 15 1964 KỌBỌ MEJI (2D)


### Oju Arinru Nri Nkan!

# Baba Onimoto Kan Gbe Anjannu Obinrin Nidi Bosi

EKO— Oju awọn arinru ati agbere ọkunrin ati obinrin nri nkan ti ẹnu ko gbọdọ sọ. Irohin ti a gbọ ni ijẹta ode yi nipa Ọgbẹni onimọto ayọkẹlẹ kan ti o nti ibi faaji bọ ni ọdọ awọn ọrẹ rẹ ni aginju oru ni Ikoyi, ti o de idi bọsi Ọbalende ti o ri obinrin arẹwa kan ti a ro rẹrẹ, ti o gbe e sinu mọto ayọkẹlẹ rẹ laimọ wipe anjannu ni obinrin na, ni o jẹki a sọ bayi.

Irohin ti a gbọ nipa baba onimọto ayọkẹlẹ ba (nwọn ni ki a forukọ on o lasiri) ni wipe bi o ti ba awọn ọrẹ rẹ ṣe faaji tijo ati ọti tan ninu ọgba awọn Oyinbo alawọdudu, kan tan ni Ikoyi ni o gbe mọto rẹ na lati ma bọ wa si ile ti o ngbe ni Surulere.

Gbara ti o di idi bọsi ni Ọbalende ni o taju kan, ti o ri obinrin ti ro aṣọ igba, ti o wọ ẹwu wulini ti o we GELE ONILEGO-RO, o si gba bata mẹsẹ.

Baba onimọto si da mọtọ duro lati gbe e gẹgẹbi nwọn ti ngbe awọn obinrin olobinrin nidi mọto yala nwọn mọ ọ ni o tabi nwọn ko mọ ri ni. Nwọn ni obinrin na juwe ile kan

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

### Ọro Olotu:

# Eru Jeje Mba Ilu!

Nigbati ẹnyin ọkawe wa 'ba nka iwe Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ yi a ku ijọ mẹta gbako ti gbogbo awọn Olotu ti nwọn nṣe akoso Ijọba wa ni Ila Orun, Ariwa ati agbede meji Iwọ orun yio fi inu lu nu, ti nwọn jọ joko jiroro le lori bi ilu yio ṣe tutu ti gbogbo wa yio jọ ri ibi gbe.

Nkan pataki ti o jọ ọrọ ti Ọlọla Tafawa Balewa tiṣe olori awọn Olotu Alakoso ilu na fẹ ba awọn sọ ko ye wa rara, sughọn a ro wipe lori bi aṣepọ wa ko ṣe ni bajẹ ni. Nkan ti o jẹki asọ bayi ni IKILỌ PATAKI ti Dokita Nnamidi Azikiwe, Gomina-agba ṣe fun gbogbo awọn Oṣelu lori ẹrọ redio nipa ipade na.

Dokita Azikiwe ni on bẹ gbogbo awọn oṣelu wa patapata ninu ẹgbẹ oṣelu ti nwọn ie wa ki nwọn le wa ki nwọn ṣe atilẹhin fun Ọlọla Tafawa Balewa Olori awọn Olotu Ijọba wa ki ipade ti nwọn fẹ ṣe na le jasi rere ki nwọn ṣe jẹki nkan ti o pawa pọ ni wa ka rara

Awa onirohin Eleti-Ọfẹ mọ wipe olotọ ọrọ ni o nla obi jade ninu apo, ninu apo, ọrọ na nio si nfa ọfa jade ninu apoo. Ọpọlọp awọn oṣelu wa ni igberiga EMI NI MO DA BAYI nyọ ẹ u. Nwọn lero wipe awọn ti gbọn ju awa

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

ẸJỌ OLOYE AWOLỌWỌ:

# Adebiyi Agbefoba Ni Jakande Ni Balogun Oro Na

EKO— Nigbati Ọgbẹni Duro Adebiyi ẹniti nṣe agbẹjọro agbefọba fun Ijọba Apapọ ilẹ Nigeria bẹrẹsi ṣe atako ẹjọ kotẹ mi lọrun ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pẹlu awọn miran ti nwọn ju sẹwọn pẹlu rẹ lori ẹsun wipe nwọn ditẹ si Ijọba pe, o ni Lateef Jakande ni Balogun gbogbo awọn ti nwọn lọwọ ninu ọtẹ na.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


## WANTED

Glass Cutters & Fixers (Skilled) only need Apply Brossette (Nigeria) Ltd.

4 WHARF ROAD,
APAPA.

# Nwon Si Ile Ise Tun tun Kan L'Eko

EKO— Ni ijẹr n ọjọ Iṣẹgun ni oloye Festus Oketie-Eboh, m is t alamojuto eto inawo Ijẹba Apapọṣe ba awọn ẹga ile iṣẹ ti awọn n p e ni African Alliance Insurance Compa y ṣ le iṣẹ ọn tuntun ti nwọn kọ si ẹ opo Broa Street L'Eko,



Alhaji S. L. Edu

Alaga awọn ti o da iṣẹ na silẹ n Alhaj S. L. Edu si sọ itan bi awọn ti ọ da ẹgbẹ na silẹ fun gbogbo a w ọ n ti o wa ba wọn ṣẹyẹ sis ile iṣẹ na.

Alhaji Edu ni awọn ko lẹ ki gbogbo ere ti awọn ba ri ko jọ lori iṣẹ na ma lo si i e ajeji ilu ... gbo ere ti o ti wọ e fun awọn lati igba ti awọn ti da iṣẹ na silẹ ni a w ọ n oke lati ṣe miran ti o e ko owo wọ ilu

O t n ṣ e alaye ... i awọn iṣe f u n g gbo awọn enia ti nwọn nṣe iṣe lọdọ awọn; o ri awọn ko si nibẹ oga iṣẹ ti e afeju pa rkinkanju awọn oṣiṣẹ na rẹ O ni ọ k a n ninu awọn oriṣẹ awọn ti awọn tan lọ si i l e Oyinbo lọ kọ iṣẹ ti pade nisisiyi o si ti njẹre iṣẹ owọ rẹ.

Oloye O ... e-Eboh ninu ọrọ tirẹ ni on kan saara si gbogbo awọn ti nwọn ... arijọ da iṣẹ na silẹ nitoripe on ri wipe ero wọn pe lọna ti n ... ro wipe awọn le ma ri owo fi ra ... iṣe miran lọwọ ni ilu wọn

# Ijoba Fe Ti Kereni Eko Fun Awon Onimoto

EKO—Awọn ẹlọpa ti gbe ikede kan jade ni ana wipe awọn fe ti kereni nla t'Eko lati ọjọ ọla lọ fun ọjọ m ẹwa gbako lati ibiti nwọn ti pin oju titi sona meji ti enia ba ... de ludo.

Awọn ọ l ọ p a ṣe alaye wipe a w ọ n onimọto ni kereni ti nwọn fe ti na a yọ lẹnu ... nitoripe ko ... saye a nsare feo fo lori kereni mọ l ... ọlẹ ojojumọ titi de owuro ọjọ keji.

A gbo wipe iṣẹ ti awọn oniwaye ... ṣe lori awọn waya tuntun ti nwọn fe fun lẹwo ilu Eko lati ilu oke ... fa titi ti nwọn fẹ ... Kereni na.

Ọrọ ... ko ba awọn ti nwọn ... fẹs rin lori Kereni na wi rara.

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri sa nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, iná-títàn ati lati mã fi yáná Kerosine ti o dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

# Owe Yoruba

1 Igbin ka ka ka ebiti ka ka ka, ebiti ti ko gbo ko le pa igbin rara Patako Efon ka, ka ... la le nla aja lenu.

2 Ika ko fe k a ru eru ki a se, eri eni ni nsoni nitoripe enia bi aparo ni aiye nfe.

## Ọlọsa mba Obinrin Lo:

# Awon Ero Onitsha Pade Agbako

BENIN CITY—Nkan kan nị ọna oju moto ti nwọn ṣeṣẹ si Bi si Eko lona ti awọn onimoto nko ero gba uitoripe o ya dẹ s'Eko Awọu ọlọsa ti bẹrẹsi da wọn lọna nibe Eyi ti o tun pabambambari nibẹ ni awọn obinrin ti o ba dara ti nwọn ba jẹ ero ninu awọn moto akero na ti awọn ọlọṣa na mba lo pẹlu ipa.

A gbọ iroh u wipe ni iwọn ibuso bi o g u n si abule kan ti nwọn npe ni Ore larin Benin s'Eko ni awọn ọ ọṣa k a n lọ da awọn onimoto lọna ni ipari ọsẹ tị o kọja yi nwọn si gba gbogbo ẹru ati owo ọwọ wọn.

Onirohin wa ni nwọn tu obinrin kan si ihoho nwọn si ba a lo pelu ipa ọkan ninu awọn obinrin ero na ti o fẹ k ọ f u n wọn wipe ki nwọn ma ba on lo nṣe ni nwọn bẹrẹsi gba a lẹnu lọtun losi sibẹ sibẹ nwọn ba a lo pẹlu ip

## Ina Isale Eko:

# Demo Fe Ran Ara Isale Eko Lowo

EKO — Irohin kan de e gbọ ... ni ... ana wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ... tun (NNDP) ... ti esi iwe ti nwọn kọ si Munisịf nipa awọn ara Isale Eko ti ina jo ile wọn gba wipe awọn yio ... ọrọ wọn si iwaju ijoko agba laipẹ yi.

Akọwe Munisịfa, Ọgbẹni S.J Mayaki fi ọkan awọn ẹgbẹ Dẹmọ balẹ wipe o da on loju wịpe awọn Igbimọ munisịfa na yio wo ikan ṣe fun awọn ti ina jo ile wọn na

A tun gbọ wịpe ninu ipade kan ti awọn ogunna gbongbo ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ paapa ṣe ni alẹ jarun, awọn na ti tẹsẹ bọ soketo, nwọn ni awọn yio fi ọgọrun pọnun £100 ran awọn ti ile wọn jo na lọwọ, nwọn ni ẹgbẹ ti o ba le ṣe bẹ, ki awọn na tẹsẹ bọ sokoto, ki nwọn da owo fun wọn

### Adefe Oja Oyinbo

Awọ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti tun kesi awọn Munisịfa ilu Eko wipe ki awọn wa ọna lati so awọn adẹtẹ ti nwọn wa ni Oyingbo kuro lọja fun anfani awọn ara ilu

Nwọn darukọ isọ mariun ti o jẹ wipe awọn adẹtẹ ni nwọn sun nibe lojojumọ nwọn nwọn fẹ ki awọn munisịfa fi na si awọn ariu isọ na ati pe ki nwọn din owo awọn isọ n2 ku si ṣile meje abọ lati sile mẹdogun.




PROGRESSIVE BUSINESS GOES FORWARD BY RAIL

If you want to expand your market or industry, you can benefit from the *dependable and low-cost* services and facilities offered by the Nigerian Railway Corporation.

Freight trains on Nigerian Railway Corporation's 1,700-mile system (plus many miles of siding) travel north and south, east and west, all the year round, day and night, providing the vital link of the vast Nigerian Federation. Industries are linked to their markets, produce centres to the ports, little villages to big towns, all along the line.

You can count on the thorough co-operation of the Nigerian Railway Corporation at the ports, produce and industrial centres and at any of its 200 and more stations.

And what's more : you are dealing with people you can trust.

SEND YOUR GOODS NATION-WIDE BY RAIL






# ELETI-OFE
(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICES & WORKS CABLE & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFE" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 28370

VOL XIV. NO 920 SATURDAY May 9 —May 15 1964


# Iwe Si Olotu

Oro Olotu:

# Awon Ale-jo Wa....

Ti ṣayin ọkawe wa ba wo inu iwe irohin wa yi daradaia, ẹ o ri irohin kan ka nibiti a gbe ti sọ wipe awọn ọmọ wa ko ti nwọn ti mu awọn baba wọn lọra lọ si ilu ajeji ni Amẹrika lati lọ fi nwọn ROKO IREKE fẹ pada wa si ile lode awọn ara wọn ni Afirika.

Awọn agbalagba Yoruba ni ile ni abọ isinmi oko; nitotọ ni ọrọ yi ṣugbọn ti awọn ara wa yi yatọ pupọ. Agbalagba ti e neare nian eko ọkan, ko nṣe lasan, ni ọrọ awọn ara wa na, bi ko ba le nkan, a jẹ wipe nkan ni o nle en na.

Awa Eleti-Ọfẹ ti gbọ irohin wipe o ti pẹ ti awọn ara wa yi ti nṣe akitikan lati pada bọ wa sile lodẹ awọn ara wọn nitoripe iwọsi ti nwọn fi nlọ wọn gẹgẹbi alawọdudu pọ. A gbọ wipe awọn ti dominira, nwọn ko tun si loko ẹru mọ, ṣugbọn iredi lati jọ gbe pọ pẹlu awọn ọmọ oluwa wọn atijọ ko ba wọn l ra mu mọ.

Awa ọmọ ilu Afirika fẹran lati ma gba awọn ajeji mọ'ra pupọ ṣugbọn ọkọ mele ẹ ia ni a mọ ti awọn ara wa, Oyinbo alawọdudu yi nko bọ? Awa paapa ti nwọn nko bọ wa ba nile a ko ti jẹun ki o ṣẹku, nṣe ni a nko ikan mẹhun, gbogbo ẹmọ ni nwọn wa nilu ti nwọn ko ri iṣẹ ṣe.

A bẹ awọn olotu Ijọba wa kakiri gbogbo ilu Afirika, ki nwọn jọwọ ba wa fi oju agba wo ọrọ awọn alejo wa na lati wa ibikan fi nwọn ha nitoripe a ki le ọmọ fun ẹkun palẹ.

Ọrọ awọn alejo wa gba irọ.

## Eto Ilu Igbaja

Ẹ ṣe pupọ Olotu fun eto ọrọ ilu wa Igbaja ti ẹ mba wa ṣe letoleto ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ. Mo fara-mọ ọrọ Ọgbẹni. Jekọbu ọmọ Igbaja ti o ni ki enikan mase da ija silẹ fun wa.

Ọba wa pẹlu awọn ijoye wa fẹran ilu wọn, nwọn ko lsi ni ri nkan ti yio mu anfani wọlu ki nwọn taa dana fun wa.

Olotu, ẹ jọwọ bi ẹ ba ti nri irohin ilu wa ni ki ẹ ma ba wa tẹ ẹ sinu iwe irohin Eleti Ọfẹ ki a le ma gbọ bi nkan ti nlọ si.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi, ẹ ko ni lu igbadi Ijọba.

Emi ni
Igbaja MosesAdetoro

## Alufa Dedeke Pada Sise Alufa

EKo —, Eni-ọwọ Alufa, Theo O. Dedeke, alufa Ijọ Ṣọṣi St. Jude no Ago Ẹgba l'Ebute-Mẹtta ti nwọn fi igba kan gba iwe alufa rẹ lọwọ rẹ wipe ko gbọdọ ṣe iwasu ni Ṣọṣi kan mọ ni a gbọ wipe Bṣọbu tuutun, Eni-ọwọ S I Kalẹ ti fun un laṣẹ wipe ki o ma ṣe ṣẹ alufa rẹ pada.

O to iwọn ọdun mẹjọ nisisiyi ti rogbodiyan kan bẹ silẹ larin Alufa Dedeke pẹlu awọn ijọ rẹ ni Ebute-Mẹtta lori ile iwe ti Ijọba fun wọn lowo wipe ki wọn kọ fun awọn ja k ẹ k ọ ni igberiko Eko kakiri.

Ologbe B i ṣ ọb u A W Howells ni o wa lori yaga nigbana ki nwọn to gba iwe aṣẹ iwasu lọwọ Alufa Dedeke ti nwọn si yan alufa miran nii si sọsi St Jude ni Agọ-Egba ni Ebute-Mẹtta.

# Eleti-Ofe D'araba


DAGENITE

BATTERIES

*give you a longer run for your money!*



# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

### Lati Owo Ayiluka

## Alhaji Kan Ku Sinu Aropileni Lona Meka

KANO — Nibiti elekun gbe nsọkun ni alayọ ayọ pẹlu ayọ ni awọn ara ileto kan ti nwọn npe ni Duwan leti Katshina fi jade nile lati lọ pade balẹ wọn, Alhaji Sulaiman, ẹni ọdun mẹrindinlọgọta, ti o lọ gun Oke Arafa ni Mẹka pẹlu ẹleha iyawo rẹ, sugbọn pẹlu ibanujẹ ni awọn ara ileto na pada s'abule wọn, nitoripe oku bale wọn na ni wọn gbe pada.

O ti ku sinu ọkọ Aropileni ti o nmu pada bọ sile. Ohun ti o ba ni ibanujẹ awọn Hausa ara abule na wa di meji nitoripe iyawo balẹ na ti o mu lọ si Mẹka ni o kọkọ ku si arin ilu Mẹka ti bale re kọ si mba inu jẹ ki iku to mu on na lọ ninu ọkọ ti o wọ.

A gbọ wipe awọn lakulaku ilu Kano ti gba oku na lọwọ awọn ara abule Duwan lati lọ yẹ e wo nitori aisan ti o pa lojiji bẹ.

## Awon Loya Kan Keran Lode Ijoba

EKO— Awọn alamojuto eto idajọ nile ẹjọ fẹ kesi gbogbo awọn adajọ ilẹ Nigeria wipe ki nwọn maṣe gba awọn agbẹjoro (lọya) kan ti nwọn jẹ ti Ijọba ni gbese owo iṣẹ ọdọdun ti awọn ma nsan laye lati ma ro ẹjọ ni iwaju wọn mọ.

A gbọ wipe o to igba enia ninu awọn loya wa ti keiti san owo-ọdọdun na ninu ijisiyi. Gẹgẹbi ofin ti Ijọba gbe sile ni iwọn nkan bi ọdun keji sẹhin, owo-ọdọdun ti awọn lọya na ma nsan ko pọ pupọ.

Awọn Loya ti nwọn ba ti nṣe iṣẹ lati bi ọdun mẹwa abọ si apo Ijọba lọ un awọn ọlọdun marun a ma san ponun marun ati abọ awon ti nwon ṣẹṣẹ de bi ọdun mẹta a ma san ponnu mẹta ati ṣile mẹta.

# Awon Ara Wa Fe Pada Wale Lati Jamaika

EKO—A gbọ wipe ogunlọgọ awọn ara wa ti ogun ati ọtẹ ti mu baba wọn lẹru lọ si ilu ajoji ni Iwọ orun Indja ni eti Amẹrika ni a gbọ wipe nwọn ọmọ wọn nsa agbara lati pada wa sile nilu Afirika,

Ni ọsẹ ti o koja awọn ọmọ ẹgbẹ kan ti a le pe orukọ wọn ni ILE NI-ABỌ-ISINMI OKO de silẹ yi lati ilu Jamaika lati wọn alamojuto Ijọba wa sọrọ bi nwọn se gba awọn ara wọn ti nwọn fẹ pada wa si ilu Afirika.

Awọn enia mẹta ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ran jade wa si ilu Afirika lati ma ba awọn Ijọba kọkan sọ ọrọ a npada bọ wa sile yi. Ọkan ninu wọn ni Ọgbẹni Filimore Alvaranga o ni awọn ... u ẹrọ na ni okunkundun pupọ O ni ọpọlọpọ awọn ara awọn lọkunrin ati lobinrin tọmọ tọmọ ni nwọn fẹ pada si Afrika.

Ọgbẹni Alvaranga ni o ju ogun ọdun lọ ti awọn ti da ẹgbẹ Ile ... a mbọ yi silẹ. O ni ti awọn ba ti kuro ni Nigeria awọn a lọ si ọdọ awọn alamojuto Ijọba Ghana, Cairo Ethiopia Tangayika ati awọn ilu bẹẹbẹ bẹ lọ ya awọn le ran awọn lọwọ nipa bibo ti awọn fẹ pada bọ wa si ilu baba baba awọn yi.

A gbọ wipe awọn Ijọba Aganyin ti ṣe ileri fun awọn ọmọ ẹgbẹ na nilu Amẹrika wipe ki nwọn fọkan balẹ awọn ni ọkọ oju omi ti awọn yio fi ko wọn pada wa si Afirika lẹlẹ.

A ko ti mọ eyiti awọn alamojuto ijọba ilẹ Nigeria fẹ ṣe nipa ọrọ awọn ara wa na.

**Eyi yi ni igbati Oloye Samuel Ladoke Akintola mba Ojagbon binrin Oyinbo kan soro lori idagba soke eto eko Ipinle Iwo, Orun.**



## Loya Kan Ni Nwan Ju 'Ogun Sinu Moto On

OKENE (Ilu Igbira) Awọn ọlọpa Ijọba Ibilẹ ilu Igbira ti ọ ko awọn kan ti Loya kan ni on fura si wipe awọn ni nwọn wa ju ogun si inu mọto fun on nitoripe ẹjọ kan ti on ṣe lowọlọwọ.

Ogunṣẹyẹ ni orukọ lọya na njẹ, a gbọ wipe ẹjọ awọn janduku oṣelu kan ti nwọn da ijọngbọn silẹ ninu ilu awọn Igbira ni o wa fun ati pe lọ,ọ ti nkan yi ṣẹlẹ ile awọn ti awọn gbe ti agbẹjọro ni o wa ti o ngbọ nkan ti o fa ija.

Lọya na ni ki on to pada si di mọto ayọkẹlẹ on awọn ti da ogun sinu rẹ nitorina ki awọn ọlọpa ba on wa idi awọn to ṣe iṣẹ buruku na.

---

O to iwọn nkan bi ago mẹwa owurọ ti ẹsẹ awọn enia ti pe si kotu daradara ko pẹ lẹhin eyi ti akọwe kotu bẹrẹ pe ẹjọ ni ikọkan ọdaran yi si wa lori ijoko ti nwọn to wọn si pẹlu awọn ẹgbẹ rẹ.

Ọdaran na bẹrẹsi si wọ tuu wosi o si nṣe gaangan ni o ba dide lojiji ti o gba ọlọpa ti o wa leti ọdọ rẹ kakakuku ti nwọn bẹrẹsi wọ gidigbo.

Lọpọlọpọ awọn ọlọpa yoku ti nwọn wa ni kotu ni akoko na ni nwọn ran ọlọpa na lọwọ lati mu u.

Warawere adajọ Ọgbẹni Alina ti ni ki awọn mu arufin na lọ si ọgba ẹwọn ki nwọn lo iti mọ boya ori rẹ lo yi.

---

## Okunri Kan Nomo Daran

EBUTE-METT — Ọgbẹni onisowo kan Samu Olọṣẹsun ni a gbọ wipe o na ọmọ alabagbe rẹ o fi pọnun ma un tan ran ni iwaju adajọ ni kotu.

Awọn ọlọpa ni ọdaran na ti on pẹlu ọga ọmọ ti o a Ezekiel Olugbemiga ni njọ gbe ile pọ ni Sv'la Street ni Ebute Metta, awọn ni nitori ilekun ile iyagbẹ ti ọmọ na si silẹ ti ko pade ni o da ija silẹ.

Awọn ọlọpa ni dipo ki ọdaran yi ṣe ikilọ fun ọmọ na wipe ki o to ti ilekun na nṣe ni o nyọ atori si, ti o si na dara, (Nigbati baba ọmọ na de ti o bere di ọrọ na lọwọ Oluṣegun ọdaran yi nṣe ni o ki atori mọlẹ ti o na on paapa ti baba ọmọ na si farapa.

Adajọ ni ki ọdaran na fi pọnun marun ta an si kotu, ti ka ba ri i san ki o lọ ṣẹwọn oṣu kan pere.

---

## Arufin Kan Woyaja Pelu Olopa Ni Kotu

IJEBU ODE—Arufin kan wọ yaja pẹlu ọlọpa kan ninu Kotu ni Ijebu ode ni ijẹrin Loju adajọ awọn ọlọpa pa pa ni ọrọ na ṣe.

---

# E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI—OFE

### ti o kun fun irohin aladun lọsọsẹ.

---

# Eleti-Ofe D'araba

---




A-mú-bọ̀lù sọ pe 'OVALTINE ni mo fi ngbéra'



*A-mú-bọ̀lù kò jẹ pa ere bọ̀lù jẹ nitoripe o nmu Ovaltine lojojumo*



Ninu ile mi gbogbo wa ni a mọ pe a kò gbodo ṣe òkùnrùn. A nmu Ovaltine lojojumo lati ní alekún agbara ati okun. Wàrà, ẹyin, kòkó ati 'vitamins' ilera miran to wà ninu Ovaltine ni a gbojulé lati fun wa ni okun fun igbokegbodo ojojumọ.



**fun ilera agbara ati okun**

*mu*

**OVALTINE**

*lojojumọ*

## Abbey Service For Sir Milton

LONDON— Mr. Duncan Sandys, the Secretary of State for Commonwealth Relations, will attend a memorial service ffor Sir Milton Margai, to be held in London at Westminster Abbey next Monday May 11.

The congregation will include other British Ministers Members of both Houses of Parliament the heads and Members of High Commissions and Embassies in London, as well as many British friends of Sierra Leone who have served the country.

## For World – Wide & Local News Read Eleti– Ofe Your Weekly Newspaper

## British Premier Welcomes Tanganyika Zanzibar Merger

LONDON— The British Prime Minister Sir Alec Douglas - Home has congratulated the leaders of Tanganyika and Zanzibar on their "... initiative" in merging the two countries, into one state.

Sir Alec has sent the following message to President Nyerere of Tanganyika (full text): May I warmly congratulate you and Vice President Karume on your wise initiative in creating the Union of Tanganyika and Zanzibar. I send you my sincere good wishes for the future happiness and prosperity of Tanganyika and Zanzibar in your new partnership.

A similar message was also sent to Vice-President Karume of Zanzibar.

## BBC 'On New Way To Learn English'

The new system of learning English spelling that is now being developed in Britain will eventually be introduced to ... educationists. This news was given in a BBC broadcast by Sir James Pitman, M P who is the leader of this new spelling movement.

Speaking in the BBC African service programme WORLD HORIZONS Sir James said that the system was already being taught in Australia, Canada, the United States and other English-speaking countries. As soon as it is ... gets going, I shall take up the question of bringing people in Africa and Asia. I think everywhere where the English language is being learnt as a second language, it will help enormously.

Sir James outlined the new system: What we've done is to realise that if you have forty sounds in English you must have forty characters or letters. Then you must use those letters in a systematic way or else you are not being alphabetic in the true sense of the word. At present, the characters in the alphabet have more than one value; and he instanced the confusion by quoting all. The pronunciation remained the same for stall. In the new system which was known as the Initial Teaching Alphabet, the word all was spelt ... ul.

The I T A was only a temporary phase in learning English. It is designed, Sir James explained, to lead up to the traditional English alphabet with its present ... of twenty six letters ... the spelling ... used in books ... room. ... feared ... necessity hardship would be cause by a period of unlearning but there was no difficulty whatever in transition. There is no unclearing about it at all it literally takes only one minute for children, once they've become fluent readers in the Initial Teaching Alphabet to become fluent readers of ordinary books. We've already had 1,500 children do this they just put down one book and pick up another.

This method of teaching was successful with both children and adults. And insofar as learning English as a second language is concerned said Sir James it will be a tremendous development for adult education. But only when ... it go over to the ... even more ... This is ... learning of English ... reading and ... as a second language.

## Read And Advertise In Eleti – Ofe Weekly Paper


## DA EHIN-DIDUN RE DURO

nipa titete mojuto awon eree inu ati apo-ito re

LO

**DeWitt's**

**Kidney & Bladder Pills**

Ki o si ba lowo awon irora ti o nko e sinu arun

LAKUREGBE, ARA-RIRO, EHIN-DIDUN ati, Awon IYONU APO-ITO



## Baba Onimoto

(O bere loju ewe kinni)

fun ni ooppo titi Ogunlana wipe ibe ni ou gbe nlo.

A gbo wipe gbara ti baba onimoto yi de korofi kan ni ojuti Ipori ti o da moto duro lati ba ebinriu soro boya on le ri "IṢẸ KOFORUN" ṣe lara re, ṣi o ba fe obinrin na ku bi mọnamọna.

Ẹru ba baba onimoto otutu si da bo o lojukanna. O ni bi on ṣe wa moto na de ile on toru ojo na on paapa alara ko le so, ṣugbọn a gbo wipe ti pe awọn onişegun babalawo fun un ki rabo rabo re ma ba pa a. Oro re o! ẹnyin onimoto a goeyawo oniyawo, Iku odo ni pa omuwe; e sora.

## Adebiyi Agbefoba Ni Jakande Ni Balogun Oro

(o bere loju ewe kinni)

Lati ibere ose yi ni Ogbeni Adebiyi, agbef'oba yi ti beresi ṣe atako gbogbo oro ti awọn loya Oyinbo mejeji ti awọn ele jo na gba lati ilu Oyinbo pelu oro awon loya eniadudu ti nwọn tun gbe iwe ofin wa si kotu-ganran ni iwaju awon agba adajo marun ti nwọn ti ngbo ejo na.

O oi awọn eleri wa si kotu lati wa so bi Jakande ti san owo okọ fun awọn, k awọn to lọ si Ghana lati lọ ko iṣe bi nwọn ti nlo ibọn.

(ko ti pari)

# Eru Jeje Mba Ilu

(O bere loju ewe kinni)

ti ayan wọn nişe lọ. Gegebi oro Olola Gomina Dokita Azikiwe o ni nwọn ko ni eko ju wa lo rara nitorina o ye ki nwọn ma kẹraro ki nwọn ma fi imoran asofin paapa kun oro wọn ninu gbogbo alamori won.

Ko si enit o le fowo soya ninu gbogbo ẹnyin okawe wa wipe lati ojo ti a ti gba ominira ni okan yin ti bale, ti ko si ewu mo ti ko si ifoya mọ.

Ki a so oro si ibiti oro wa, gbogbo wa ni ẸRU JẸJẸ MBA LOJOJUMO nipa bi ore awon oṣelu wa ti nlo si. "OJU WỌN Ni A NRI LOJOJUMO, A KO MỌ INU WỌN. Oro wọn na wa dabi oruko oloruko ARALAMO.

Oto ni iṣe ti a ran wọn lọ sile igbimo fun ṣugbọn ti nwọn ba ti de ọhun tan iṣe ti ara wọn bi nwọn yio ti d'olowo d'olola ni nwọn nma nwa. Boya Oluwa Olodumare le jeki nwọn gbo ikilo ula ti Gomina agba ki fun won yi ki nwọn wa ona ti nwọn yio fi le sin ilu, kiṣe ki awa ilu ma sin wọn ki a le ri ere ko lodo Ijoba.

Ẹyin ara ilu, eru jeje mba wa o:

## Ibukun Ni Iranti Olododo



Ologbe Herbert Macaulay

Eniti o wa ninu aworan yi ni Ologbe Eninigboro Herbert Samuel Heelas Macaulay ti o di ologbe ni ojo keje osu Karun odun 1946 eden kokandilogun le hin.

Ologbe ni Eniti o fi tokan-tokan ja fun ire ati anfani ilẹ Nigeria ki o to jalaisi.

O we okun-we esa; mu opa bo wa sile, oju gbogbo wa tọse. Mase je okun, Mase jo ekolo Suare


THE ANSWER TO
TROPICAL CONDITIONS
★
UNMATCHED
AFTER SALES
SERVICE
★
MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Phone 283/0; Editor, (Oloye) Ola Onatade 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 467 Lagos.